# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OSÙ KEJE, ỌDÚN 2024**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**Ìsìn Omi Iná**

**OṢÙ KÉJE, ỌDÚN 2024 – ÌSÌN OMI INÁ**
**ÀWỌN ORIN ÌBẸ̀Ẹ̀RẸ̀**

1. **Orísun igbàlà kíkún! Orísun igbàlà kíkún!**

Sí sílẹ̀ fún gbogbo wa,
Lát'Ọ̀dò Olùgbàlà wà,
Ló nṣàn yí gbogb'ayé ká;
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

2. Ìran ológo li èyí

Ìsun ìwẹ̀nùmọ́ nṣàn,
Ó nwẹ gbogbo abàwọ́n nù,
Ti ìdálẹ́bi ẹsẹ̀,
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ẹ̀jẹ̀ tí nwẹ̀ mọ́ láúláú.

3. Ìsun ijìnlẹ̀ ìfẹ́ Rẹ

Nṣàn ní inú ọkàn wa;
Ó nwẹ gbogbo erò aìmọ́,
K'a lè wà láílàbàwọ́n,
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

4. Ìsun iyè aìnìpẹ̀kùn,

Láti ọ̀run nṣàn sí wa,
Ọlọ́run dàpọ̀ pẹ̀lú wa,
Idàpọ̀ t'ó dùn jùlọ;

Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

5. Àníyàn àti ìyèméjì, òkùnkùn òn ‘bànújẹ́,
Ẹ̀rù àti ẹkún kì íṣe t’èmi mọ́,
‘Gbàgbọ́ kò mọ òkùnkùn ọ̀la,
Tor’Ólúgbàlà mi ti lọ síwájú,
Ìsun ìgbàlà kíkún, ó kún títí láíláí

1. **Ọlọ́run t’Ó mú Ísráẹ́lì la òkun já.**
Tí Ó sì gbà wọ́n kúrò lí oko ẹrú,
Tí Ó rọ̀’jò ónjẹ sílẹ̀ láti ọ̀run,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

**Ègbè**
Ọ̀kan ná lónì, ọ̀kan ná lónì,
B’ákokò tí Ó sin Ísráẹ́lì la òkun;
Ọmọ Rẹ̀ ní un ó jẹ̀, ‘torí ọ̀rọ̀ Rẹ́ sọ
Pé, ọ̀kan ná nì Ọlọ́run
Ìyanu lónì.

2. Ọlọ́run t’Ó gba Dáníẹ́lì lọ́wọ́ Kinìún,
T’Ó sì yọ àwọn mẹ́ta n’nú iná’léru,
Ẹni tí àwọn ìràwọ̀ ngbà Tirẹ̀ gbọ́,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

3. Ọlọ́run t’Ó f’ọ̀rọ̀ Rẹ̀ d’áfẹ́fẹ́ dúró,
T’Ó sì nsọ ‘bànújẹ́ òní d’ayọ̀ lọ́la,

Ẹni tí Ó yí òkúta ‘bojì kúrò,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

4. Ọlọ́run t’Ó wọ itànná ìgbẹ́ l’áṣọ,
Ẹni t’Ó mú omi ṣàn n’íyàngbẹ́ ilẹ̀,
Tí Ó wẹ ẹlẹ́ṣẹ̀ mọ́ nínú èrí rẹ,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

## <u>Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA</u>

1. Olúwa, nínú ètò yìí lónì, pàṣẹ kí ìmọ́lẹ̀ Rẹ tàn sínú òkùnkùn mi, ní orúkọ Jésù.
2. Agbárakágbára tí ó kórajọpọ̀ lòdì sí ayànmọ́ mi yóò gba iná lónì, ní orúkọ Jésù.
3. Olúwa, bí a bá ṣe dá orúkọ Jésù níyìn lónì, jẹ́ kí orísun àwọn iṣòro mi gbẹ dànù, ní orúkọ Jésù.
4. Olúwa, mo gbé ayé mi síwájú Rẹ lónì, jẹ́ kí a fọ ìpìlẹ̀ ayé mi nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti gbógun dìde lòdì sí ẹ̀rí mi, ṣubú lulẹ̀, kí o sì kú lónì, ní orúkọ Jésù.
6. Ẹ̀yin adigunjalè ayànmọ́ ilé bàbá mi, itẹ́kù yín rè é, ẹ túmisílẹ̀ kí ẹ sì kú, ní orúkọ Jésù.
7. Ara, ọkàn àti ẹ̀mí mi, gbọ́ Ọ̀rọ̀ Olúwa; ẹ ti irúgbìn sátánì jáde báyì, ní orúkọ Jésù.

# ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Orin Dáfídì 62:11:** Ọlọ́run tí sọ̀rọ̀ lẹ́kàn; lẹ́rìnkejì ni mo gbọ́ èyí pé: ti Ọlọ́run li agbára.

**Orin Dáfídì 89:13:** Ìwọ ní apá agbára: agbára lí ọwọ́ Rẹ, gíga li ọwọ́ ọ̀tún Rẹ.
**Orin Dáfídì 40:13:** Kí ó wù Ọ́, Olúwa, láti gbà mí: Olúwa, yára láti ràn mí lọ́wọ́.

**Orin Dafidi 107:20:** O ran ọrọ Rẹ, O si mu wọn lara da, O si gba wọn kuro ninu iparun wọn.

**Orin Dafidi 147:3:** O mu awọn onirora aya lara da: O di ọgbẹ wọn.

**Orin Dáfídì 6:2:** Olúwa, ṣànú fún mi; nítorí àìlera mi: Olúwa, mú mi lára dá; nítorí tí ara kan egungun mi.

**Orin Dáfídì 103:2-5** Fí ibùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo ore rẹ̀: Ẹnití ó dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì; ẹnití ó sì tán gbogbo àrùn rẹ, Ẹnití ó ra ẹ̀mí rẹ kúrò nínú ìparun; ẹnití ó fi ìṣeun-ìfẹ́ àti ìyọ́nú dé ọ lí adé. Ẹnití ó fi ohun dídára tẹ́ ọ lọ́rùn: bẹ́nì ìgbà èwe rẹ di ọ̀tun bí ti idì.

**Orin Dáfídì 30:2:** Olúwa Ọlọ́run mi, èmi kígbe pè ọ́, ìwọ sì ti mú mi lára dá.

## <u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ẹ̀yin ángẹ́lì Ọlọ́run Alààyè, ẹ lé àwọn aléni-mádẹ́yìn mi sínú òkun pupa, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára ìkà ilé bàbá mi tí wọ́n yàn láti ṣi ayànmọ́ mi nípò, kú nípa iná, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo àjàgà tí wọ́n yàn láti ṣi ayànmọ́ mi nípò lọ sí ẹ̀yìn, kúrò lọ́nà, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, jẹ́ kí òróró tí yóò jẹ́ kí n ṣe àjọyọ̀, bàlé ayànmọ́ mi báyì, ní orúkọ Jésù.
7. Èmi yóò dìde nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́, èmí yóò fi ẹlẹ́yà mi ṣẹ̀sín, ní orúkọ Jésù.